# A TÚN MAJẸMU NAA DÁ

## Ẹksodu 34:1-35

## ẸKỌ 69 FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI:“Nitori eyi ni ifẹ Ọlọrun, pe ki awa ki o pa ofin rẹ̀ mọ́: ofin rẹ̀ kò si nira”(1 Johannu 5:3).**

Nigba kin-in-ni ti Mose dahun ipe Ọlọrun lati lọ sori Oke Sinai, ki o ba le gba Ofin, Ọlọrun kọ Ofin Mẹwaa naa sinu wàlaa okuta meji ti O ti pese silẹ, O si sọ fun Mose lati gbe wọn pada sọdọ awọn eniyan naa.

### Ọna si Ayọ̀

A fi Ofin fun ni lati kọ́ wa bi a ṣe le gbe igbesi aye ti yoo mu wa layọ ninu ayé yii, ati lati fihàn wọn ohun ti Ọlọrun n fẹ lati mura wọn silẹ fun Ọrun. Ofin kin-in-ni ni, “Ki iwọ ki o si fi gbogbo àiya rẹ, ati gbogbo ọkàn rẹ, ati gbogbo agbara rẹ fẹ́ OLUWA Ọlọrun rẹ” (Deuteronomi 6:5). Bawo ni ẹni ti o ba fẹ Oluwa pẹlu gbogbo àyà, ọkàn ati agbara rẹ yoo maa huwa? Njẹ ayé ko ha ni jẹ ibi ayọ, bi olukuluku eniyan ti ó wà ninu rẹ̀ ba n gbé igbesi aye rẹ̀ gẹgẹ bi ofin Ọlọrun? Kò ni si imọ-tara-ẹni nikan tabi ojukòkòrò tabi ikorira; olukuluku ni yoo fẹran ẹni keji rẹ.

Ọlọrun mọ̀ pe ẹṣẹ ti o wà lọkan awọn eniyan ni o fa gbogbo wahala wọn, O si fẹ pa awọn eniyan ti Rẹ̀ mọ́ kuro ninu wahala naa. O fẹran wọn: O pe wọn ni “akọbi” Rẹ̀, eyi ti i ṣe ẹni ti o dagba ju lọ, ti yoo maa jẹ orukọ ẹbi lọ titi. O fẹ jẹ Baba fun wọn, ki wọn si le maa fi orukọ Rẹ̀ pe wọn.

Ẹ jẹ ki a ro iru ayọ ti awọn Ọmọ Israẹli i ba ni, bi o ba ṣe pe wọn fẹ lati fẹran Ọlọrun ati lati gbọran si aṣẹ Rẹ̀. Ọlọrun ṣeleri pupọ fun wọn, bi wọn ba saa ti le ju ọkan wọn silẹ fun Un: “Irú ọkàn bayi iba ma wà ninu wọn, ki nwọn ki o le ma bẹ̀ru mi, ki nwọn ki o si le ma pa gbogbo ofin mi mọ́ nigbagbogbo, ki o le dara fun wọn, ati fun awọn ọmọ wọn titilai!” Ṣugbọn ọlọrùn-lile eniyan ni wọn, wọn si kọ̀ ifẹ Rẹ̀, nitori naa ni wọn si ṣe bọ́ sinu wahala pupọ

### Wọn kì Yoo Gbọ́

Awọn Ju ti wọn wà nigba aye Jesu ṣe aibikita ifẹ Rẹ̀ bẹ́ẹ̀. Ni oru ọjọ kan, Jesu Olugbala wa joko lori oke, ti o doju kọ ilu Jerusalẹmu, inu Rẹ̀ si bajẹ lọpọlọpọ. Awọn eniyan ti O wá lati gbà la n gbe ninu ile ti o lọ wọọrọ ti o si rọ̀ wọ́n lọrun ninu ilu naa, ṣugbọn wọn ko ri àye fun Un. O wá lati fun ọkàn wọn ni alaafia ati ayọ ti ko lẹgbẹ, ṣugbọn wọn ko jẹ gbọ́ ti Rẹ̀. Igbe Rẹ̀ ni alẹ ọjọ na ni: “Jerusalẹmu, Jerusalẹmu, … igba melo li emi nfẹ radọ bò awọn ọmọ rẹ, bi agbebọ̀ ti iradọ bò awọn ọmọ rẹ̀ labẹ apá rẹ̀, ṣugbọn ẹnyin kò fẹ!” (Matteu 23:37).

Bi Jesu ti fẹran awọn eniyan to lọjọ oni ni yii, awọn angẹli ni Ọrun paapaa, a maa yọ̀ nigba ti ọkàn kan ba ronupiwada. Gbogbo ibukun ti a le ronu rẹ̀, ni o n tẹle igbesi aye Onigbagbọ, sibẹ ọpọ eniyan ni o kọ̀ lati wá sọdọ Jesu, wọn kọ̀ lati ronupiwada ẹ̀ṣẹ wọn ki wọn si gbe igbesi aye ti yoo wu Ọlọrun.

### Walaa Okuta ti a kọ Ofin sí Fọ́

Nigba ti Mose wà lori oke lati gba awọn ofin iyebiye wọnni lati ọdọ Ọlọrun, alagidi Israẹli ṣe ẹgbọrọ maluu wura lati sìn, bi o tilẹ jẹ pe Ọlọrun ṣẹṣẹ sọ fun wọn pe wọn ko gbọdọ yá ere kan lati fori balẹ fun tabi lati sin. Nigba ti Mose ri ohun ti awọn eniyan naa ṣe inu bi i pupọ si ẹṣẹ wọn to bẹẹ ti o fi sọ wàlaa okuta Ọlọrun silẹ, wọn si fọ́.

Bawo ni o ti ba ni ninu jẹ to, pe a fọ́ walaa okuta iyebiye ti Ọlọrun! Ṣugbọn bawo ni o ti buru jù lọ to pe gbogbo awọn eniyan naa ti ṣe aigbọran si Ọlọrun! Mose ni lati gbadura kikankikan fun igba pipẹ ki Ọlọrun ba le dariji awọn eniyan naa. “Mo si wolẹ niwaju OLUWA li ogoji ọsán ati li ogoji oru, bi mo ti wolẹ niṣaju; nitoriti OLUWA wipe, on o run nyin. Mo si gbadura sọdọ OLUWA wipe, Oluwa ỌLỌRUN, máṣe run awọn enia rẹ ati iní rẹ, ti iwọ ti fi titobi rẹ ràsilẹ, ti iwọ mú lati Egipti jade wá pẹlu ọwọ́ agbara” (Deuteronomi 9:25, 26).

Ọlọrun dahun adura yii, O si sọ fun Mose lati ṣe walaa okuta meji miiran, gẹgẹ bi ti akọkọ, pe Oun yoo si tun kọ Ofin naa. Mose gun ori oke lọ ni kutukutu, Ọlọrun si ba a sọrọ lati inu ọwọ̀n awọsanma.

### Oore-ọfẹ ni a fi Gbà Wá Là

Oluwa rán Mose leti pe aanu nikan ni o jẹ ki Oun tun sọ majẹmu Oun dọtun pẹlu awọn eniyan naa. Awọn Ọmọ Israẹli ko le ṣe ohun kan lati ri oju rere Rẹ̀. Oore ati ipamọra Rẹ̀ ni o mu Un gbọ ẹbẹ Mose ti Oun ko si pa orilẹ-ede buburu yii run.

Ko si ohun kan ti ẹlẹṣẹ le ṣe lonii ti o le mu un de Ọrun, tabi ki o ri oju rere Ọlọrun. Ninu aanu Rẹ̀ ni O rán Ọmọ Rẹ̀, Jesu, lati ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ fun igbala wa. Ko si iṣẹ rere kan ti a ṣe ti o le gbe wa de iye ainipẹkun. Kò si si ẹni ti o le wi pe oun ko buru pupọ ju nitori bẹ o dá oun loju pe Ọlọrun yoo gba oun si Ọrun. Iwe Mimọ wi pe: “Gbogbo enia li o sá ti ṣẹ̀, ti nwọn si kuna ogo Ọlọrun” (Romu 3:23). Ẹlẹṣẹ ni olukuluku eniyan jẹ́ titi yoo fi wá sọdọ Jesu pẹlu ironupiwada, ti yoo si beere fun idariji, yoo rán Ọlọrun leti pe Jesu ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ ki “ẹnikẹni ti o ba gbá a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni ìye ainipẹkun” (Johannu 3:16). Nigba ti a ba dari ẹṣẹ wa ji wa, Oluwa yoo fun wa ni agbara lati má dẹṣẹ mọ́: “Ẹnikẹni ti a ti ipa Ọlọrun bí, ki idẹṣẹ” (1 Johannu 3:9).

**Awọn Ileri Rẹ̀**

Eredi miiran wà ti Ọlọrun fi ṣe aanu: O ti ṣe ileri fun Abrahamu, Isaaki ati fun Jakọbu pẹlu pe, iru ọmọ wọn ni yoo jogun, ti wọn yoo si ṣe akoso ilẹ Kenaani. Ni akoko ẹkọ wa yii, awọn ara Kenaani, Hitti, Perissi, Hifi ati Jẹbusi ni wọn n gbé nibẹ; wọn jẹ orilẹ-ede ti o lagbara ju awọn Ọmọ Israẹli lọ. Ṣugbọn Ọlọrun wi pe Oun yoo pa majẹmu ti Oun ti ba awọn patriaki iṣaaju dá mọ́, Oun yoo ba Israẹli lọ, Oun yoo si ràn wọn lọwọ lati ṣẹgun ilẹ naa. O wi pe Oun yoo ṣe iṣẹ iyanu ti o ju eyi ti o ti ṣẹlẹ tẹlẹ ri -- iṣẹ-iyanu ti o ju awọn ajakalẹ-arun Egipti paapaa lọ. Nigba ti Ọlọrun ba wa niha alailagbara, ko si bi agbara ogun ọta naa ti le pọ tó, awọn ti o ba wà niha ti Oluwa ni yoo ṣẹgun. "Ogun na kì iṣe ti nyin bikòṣe ti Ọlọrun" (2 Kronika 20:15).

**Kò si Irẹpọ pẹlu awọn Ẹlẹṣẹ**

Ọlọrun ṣeleri pe Oun yoo fun awọn eniyan Rẹ̀ ni iṣẹgun lori ọta wọn, ṣugbọn wọn gbọdọ maa ba wọn lò gẹgẹ bi ọta. Wọn kò gbọdọ ba wọn da nnkan pọ̀ nitori awọn ara Kenaani n sin oriṣa, wọn si le mu ki awọn Ọmọ Israẹli sin oriṣa. A ranti ẹgbọrọ maluu wura, a si le ri eredi ti Ọlọrun fi n kilọ fun wọn kikankikan lati sá fun ibọriṣa.

Awa pẹlu, gbọdọ ṣọra ki a má ba kẹgbẹ ayé. Bi a ba fẹ lati ba awọn ẹlẹṣẹ kẹgbẹ ju awọn Ọmọ Ọlọrun lọ, o yẹ ki a yẹ ara wa wò. "Ẹ kò mọ̀ pe ìbarẹ́ aiye iṣọtá Ọlọrun ni?" (Jakọbu 4:4). Jesu n fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ jẹ ẹni ọ̀tọ. O ti pe wọn ni "iṣura ãyo" ti Rẹ̀, O si fẹ ki wọn pa ara wọn mọ́ lailábàwọ́n kuro ninu ayé.

**Ogo Ọlọrun fara Hàn**

Nigba ti Mose pada bọ̀ lati ori oke, oju rẹ̀ n dán pẹlu ogo nla nitori o ti bá Ọlọrun pade. Ẹru ba awọn Ọmọ Israẹli lati wo oju rẹ titi o fi fi ibojú bo oju rẹ. Ẹ jẹ ki a ro iru ogo ti o tẹle fifun ni ni Ofin Mẹwaa; ki a si ranti nigba naa pe Ọlọrun ti fun wa ni majẹmu ti o tobi ju eyi lọ ni igba aye Ẹmi Mimọ́ yii. Nigba naa Ọlọrun kọ Ofin sinu wala okuta; nisisiyii O kọ ọ sinu ọkàn awọn ti o gbagbọ́. Rò bi ogo ti a oo ni yoo ti pọ tó, nigba ti a ba wá sọdọ Oluwa pẹlu Ẹjẹ Jesu ninu ọkàn wa lẹyin ti a ti ri igbala ati isọdimimọ, ti a bá si gbà ifiwọni Ẹmi Mimọ́. A ti mu iboju naa kuro, olukuluku wa si le gbadùn ibarẹ ati ibalo Ọlọrun.

Nigba isọji ni ibi kan ni India, Ẹmi Mimọ́ sọkalẹ lojiji sori awọn ti wọn pejọ pọ lati gbadura ninu ile isin. Adura naa dún bi iro omi nlá. Awọn ara ilu sare de, nigba ti wọn si ri ayọ pupọ ti awọn ti wọn gba agbara Ẹmi Mimọ wọnyii ni, wọn pada lọ, wọn wi pe "Awọn Onigbagbọ ti ri Ọlọrun wọn." Lati ni iru iriri agbara Ẹmi Mimọ́ yii jẹ anfaani olukuluku Onigbagbọ ti o n gbe igbesi-aye ti o wu Oluwa ti o si n pa gbogbo ofin Rẹ̀ mọ́.

**AWỌN IBEERE**

1. Bawo ni a ṣe fi Ofin Mẹwaa fun Mose?
2. Ki ni ṣẹlẹ si awọn wàlaa okuta ti iṣaaju?
3. Ki ni ṣe ti Ọlọrun kò fi pa awọn Ọmọ Israẹli run? Eredi meji.
4. Ki ni ofin kin-in-ni?
5. Ki ni ṣe ti a gbọdọ ṣọra lati má ba awọn ọrẹ ayé kẹgbẹ pọ̀?
6. Bawo ni a ṣe le "ri" Ọlọrun?